# IṢỌTẸ ISRAẸLI SI ỌLỌRUN
## Numeri 14:1-45
### ẸKỌ 102 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Ibukún ni fun enia na, ipá ẹniti o wà ninu rẹ: li ọkàn ẹniti ọ̀na rẹ wà. Awọn ti nla afonifoji omije lọ, nwọn sọ ọ di kanga" (Orin Dafidi 84:5, 6).**

**I Ibẹrubojo Awọn Ọmọ Israẹli**

1. Gbogbo ijọ eniyan sọkun ni gbogbo òru nitori ihin buburu awọn ami mẹwaa, Numeri 14:1; 13:33
2. Wọn kùn si Mose ati Aaarọni, wọn n bẹru ohun ti yoo de ba awọn ọmọ wọn ju Ọlọrun lọ, Numeri 14:2, 3; Ifihan 21:8
3. Wọn gbero lati yan olori fun ara wọn ki wọn si pada si Egipti, Numeri 14:4; 1 Kọrinti 10:11

**II Ẹbẹ̀ Awọn Alakoso Wọn**

4. Mose ati Aarọni doju wọn bolẹ niwaju gbogbo ijọ eniyan Israẹli, Numeri 14:5
5. Joṣua ati Kalebu fa aṣọ wọn ya, wọn bẹ awọn eniyan naa ki wọn má ṣe ṣọtẹ si Ọlọrun, Numeri 14:6-9
6. Ṣugbọn awọn ijọ fẹ sọ Joṣua ati Kalebu lokuta, lẹsẹ kan naa ogo OLUWA si kún Agọ-ajọ, Numeri 14:10

**III Idajọ OLUWA Rọ̀ Dẹdẹ sori Israẹli**

7. O mura lati fi ajakalẹ-arun kọlu wọn ki o si sọ Mose di orilẹ-ède nla, Numeri 14:11, 12; Ẹksodu 32:10
8. Gẹgẹ bi onilaja fun Israẹli Mose gbadura pe ki Ọlọrun dá wọn sí fun ogo Rẹ̀, Numeri 14:13-19; Ẹksodu 32:12
9. OLUWA si dariji Israẹli gẹgẹ bi ibeere Mose, Numeri 14:20

**IV Awọn Agbagba Ninu Wọn ni Yoo Kú ni Aginju**

10. Bi wọn ti dan Ọlọrun wo ni igba mẹwaa yii, wọn ki yoo rí Ilẹ Ileri naa, Numeri 14:21-25; Matteu 4:7
11. A fun wọn ni ogoji ọdun lati fi rìn kiri, awọn ọmọ wọn nikan ni yoo si wọ ilẹ naa, Numeri 14:26-35; Heberu 4:1, 2
12. A fi àrùn kọlu awọn amí mẹwaa naa, a si dá Joṣua ati Kalebu nikan sí lati wọ ilẹ naa, Numeri 14:36-38, 24, 30

**V Aṣeti Israẹli lati Wọ Ilẹ Naa**

13. Wọn dide lowurọ kutukutu ninu imọ̀ ara wọn lati wọ Ilẹ Ileri naa, Numeri 14:39, 40
14. Mose kilọ fun wọn ki wọn má ṣe ré aṣẹ OLUWA kọja, Numeri 14:41-43
15. Mose duro ninu Agọ-ajọ, ṣugbọn wọ́n gòke lọ, awọn ará Amaleki si bori wọn, Numeri 14:44, 45

## ALAYE

**Ẹṣẹ Aigbagbọ́ Israẹli**

Ikuna Israẹli, lẹyin ti a ti mu wọn de eti Ilẹ Ileri ti OLUWA si paṣẹ fun wọn lati lọ gbà á, jẹ apẹẹrẹ nla gidigidi ninu iwe itan lati fi han ni ohun ti **aigbagbọ** i maa ṣe ni igbesi-aye eniyan. Ni atetekọṣe nigba ti Eṣu sọ fun obinrin ni pe, "Õtọ li Ọlọrun wipe?" ọwọ rẹ̀ tẹ anfaani kan lati gbin irugbin aigbagbọ sinu ọkàn eniyan. Awọn ẹmi eṣu paapaa gbagbọ wọn si wariri, ṣugbọn Bibeli fi ye ni nipa awọn Ọmọ Israẹli pe aigbagbọ ni olori ẹṣẹ wọn eyi ti o si fa iṣubu orilẹ-ede yii nikẹyin. Ẹṣẹ aigbagbọ yii kan naa ni o n rán aimoye ọkẹ eniyan lọjọ oni lọ si ègbé ainipẹkun.

A fi ye ni ninu ẹkọ wa ti o kọja pe nigba ti awọn Ọmọ Israẹli de eti ilẹ Kenaani, wọn gba Mose niyanju pe ki a rán awọn amí lati lọ rin ilẹ naa wò. Lai si aniani, wọn rò pe eyi gan an ni ohun ti o tọ́ lati ṣe. Ṣugbọn Ọlọrun ti O mọ ọkàn ọmọ eniyan mọ ohun ti o wa labẹ imọran yii. Ilẹ Ileri yii ko ṣajeji si awọn Ọmọ Israẹli, nitori Ọlọrun ti sọ fun wọn nipa ibukun ti o wà nibẹ O si ti fi ọkàn wọn balẹ pe Oun yoo jà fun wọn. I ba ṣe pe awọn eniyan yii ti ni igbẹkẹle ninu Ọlọrun eyi ti oore Rẹ si wọn, ati iṣẹ iyanu Rẹ ti O ti ṣe latẹyinwa yẹ ki o rú soke ninu wọn, wọn i ba ti gba ọrọ ti Ọlọrun sọ fun wọn gbọ́, wọn i ba si ti goke lẹsẹkẹsẹ lati lọ gba ilẹ naa gẹgẹ bi Ọlọrun ti palaṣẹ fun wọn. Ṣugbọn nitori wọn ni ọna miiran, Ọlọrun fi wọn silẹ lati mu ifẹ inu wọn ṣẹ pẹlu abayọrisi ibi ti aigbagbọ wọn mu ba wọn.

Nigba ti awọn amí mejila wọnyii pada bọ̀, wọn royin pe bi OLUWA ti wi gan an ni ilẹ naa ri -- ilẹ ti o n ṣàn fun wara ati fun oyin -- wọn si mu eso ilẹ naa wá lati fi iru ibukun ti o wà nibẹ hàn. Ṣugbọn ṣá – "ilu olodi ni ilu wọn", awọn "omiran" si wà ni ilẹ naa pẹlu! Nigba ti awọn amí mẹwaa wọnyii si pari iroyin buburu wọn, ẹru wọ inu ọkàn awọn Ọmọ Israẹli, eyi si ni iṣisẹ keji si aigbagbọ. Wọn sọkun ni gbogbo oru naa pe, "Awa iba kuku ti kú ni ilẹ Egipti" tabi "Awa iba kú li aginju yi." Wọn si tun n foya ohun ti o le de ba awọn ọmọ wọn, wọn si kigbe pe, "Awọn ọmọ wa yio di ijẹ." Ohun ti o tẹle e ni pe wọ́n bẹrẹ si kùn si Mose ati Aarọni, wọn si n gbero lati yan olori ti yoo mú wọn pada si Egipti. Bayii ni wọn ṣọtẹ si Oluwa.

Awọn meji ninu awọn amí, Joṣua ati Kalebu, pẹlu ri awọn ilu olodi, awọn orilẹ-ede alagbara ati awọn omiran ilẹ naa. Ṣugbọn eyi kò daya fò wọn nitori wọn ni igbagbọ ninu Ọlọrun. Wọn ranti iṣẹ iyanu ti O ti ṣe ati ileri ti O ti ṣe pẹlu. "Nwọn si sọ fun gbogbo ijọ awọn Ọmọ Israẹli wipe, Ilẹ na ti awa là já lati ṣe amí rẹ̀, ilẹ na dara gidigidi. Bi Oluwa ba fẹ́ wa, njẹ yio mú wa wọ inu ilẹ na yi, yio si fi i fun wa; ilẹ ti nṣàn fun warà ati fun oyin. Ṣugbọn ẹ máṣe ṣọ̀tẹ si OLUWA, bẽni ki ẹ máṣe bẹ̀ru awọn enia ilẹ na; nitoripe onjẹ wa ni nwọn, àbo wọn ti fi wọn silẹ, OLUWA si wà pẹlu wa" ẹ máṣe bẹ̀ru wọn" (Numeri 14:7-9). Ṣugbọn gbogbo ijọ eniyan mura tan lati sọ wọn ni okuta, bi o tilẹ jẹ pe ogo OLUWA farahan lori Agọ-ajọ niwaju gbogbo awọn Ọmọ Israẹli.

**Idajọ Ọlọrun lori Israẹli**

Ni akoko yii ni OLUWA dide ti O sọ fun Mose pe, "Awọn enia yi yio ti kẹgàn mi pẹ tó? yio si ti pẹ tó ti nwọn o ṣe alaigbà mi gbọ́, ni gbogbo iṣẹ-àmi ti mo ṣe lãrin wọn? Emi o fi ajakalẹ-àrun kọ lù wọn, emi o si gbà ogún wọn lọwọ wọn, emi o si sọ iwọ di orilẹ-ède nla, ati alagbara jù wọn lọ" (Numeri 14:11, 12). Ṣugbọn Mose, gẹgẹ bi apẹẹrẹ Alagbawi nla ni, dide fun iranwọ awọn eniyan yii o si bẹbẹ niwaju OLUWA. O rán OLUWA leti iru ọwọ́ agbara ti O fi mu wọn jade lati Egipti wá, ati bi O si ti pa wọn mọ́ titi wọn fi de eti bebe Ilẹ Ileri naa. Ki ni awọn orilẹ ede yoo ha wi bi a ba pa awọn eniyan yii run? "Njẹ bi iwọ ba pa gbogbo awọn enia yi bi ẹnikan, nigbana li awọn orilẹ-ède ti o ti gbọ́ okiki rẹ yio wipe, Nitoriti OLUWA kò le mú awọn enia yi de ilẹ ti o ti fi bura fun wọn, nitorina li o ṣe pa wọn li aginjù. Njẹ nisisiyi, emi bẹ̀ ọ, jẹ ki agbara OLUWA ki o tobi, gẹgẹ bi iwọ ti sọ ri pe, Olupamọra ati ẹniti o pọ̀ li ãnu li OLUWA ti ndari ẹ̀ṣẹ ati irekọja jì, ati bi o ti wù ki o ri, ti ki ijẹ ki ẹlẹbi lọ laijìya; a ma bẹ̀ ẹ̀ṣẹ awọn baba wò lara awọn ọmọ, titi dé iran kẹta ati ẹkẹrin. Emi bẹ̀ ọ, dari ẹ̀ṣẹ awọn enia yi jì, gẹgẹ bi titobi ãnu rẹ, ati bi iwọ ti darijì awọn enia yi, lati Egipti titi di isisiyi" (Numeri 14:15-19). Bi ẹṣẹ Israẹli ti tobi to ni, sibẹ OLUWA gbọ ẹbẹ Mose, O si dariji wọn. Titobi ni aanu Ọlọrun, "On ki iṣe si wa gẹgẹ bi ẹ̀ṣẹ wa; bẽni ki isan a fun wa gẹgẹ bi aiṣedede wa" (Orin Dafidi 103:10).

Sibẹ Israẹli ko ṣe alaijiya. Ẹlẹṣẹ ki yoo lọ laijiya. Ẹnikẹni ti o ba mookun ninu ẹṣẹ, lẹyin ti o ti ri imọlẹ, ko gbọdọ reti pe oun yoo bọ́ lọwọ idajọ Ọlọrun olododo. Dafidi paapaa mọ ijiya ti ẹ̀ṣẹ nla ti o ṣe mu ba a, lẹyin ti OLUWA ti dariji i. Bakan naa ni a rán idajọ ti o tọ sori Israẹli ọlọtẹ. Awọn eniyan wọnyii ti ṣe idajọ fun ara wọn nigba ti wọn wi pe, "Awa iba kú li aginjù yi." Nitori Ọlọrun pinnu pe awọn Ọmọ Israẹli yoo wà ni aginju fun ogoji ọdun, wọn o si maa rin kiri ninu aginju kan naa, ọdun kan fun ọjọ kan ti awọn amí lò lati rin ilẹ Kenaani wò, titi gbogbo awọn eniyan ti o ṣọtẹ si OLUWA, tọkunrin tobinrin yoo fi kú tán ni aginju. Awọn ọmọ wọn ti wọn ro pe yoo di ijẹ, ni a mu lọ si Ilẹ Ileri naa. Ninu ọgbọ̀n ọkẹ ọkunrin ti o ti to ọmọ ogún ọdún tabi ju bẹẹ lọ ti o jade ni Egipti, ẹni meji pere, Joṣua ati Kalebu, ni o dé Ilẹ Ileri naa – nitori wọn ni "ọkàn miran." Ṣugbọn awọn amí mẹwaa iyoku ti o mú ki Israẹli kùn, "ani awọn ọkọnrin na ti o mú ihin buburu ilẹ na wá, nwọn ti ipa àrun kú niwaju OLUWA" (Numeri 14:37).

**Igbiyanju Israẹli lati Wọ Kenaani**

Nigba ti Mose sọ idajọ Ọlọrun ti o le ṣugbọn ti o tọna fun awọn Ọmọ Israẹli, wọn ṣọfọ gidigidi, ṣugbọn ko si ironupiwada ninu ọ̀fọ wọn. Nitori wọn dide ni kutukutu owurọ, wọn si gun ori oke lọ, wi pe, "Kiyesi i, awa niyi, awa o si gòke lọ si ibiti OLUWA ti ṣe ileri: nitoripe awa ti ṣẹ̀: (Numeri 14:40). Ṣugbọn Mose wi pe, "Ẽṣe ti ẹnyin fi nre aṣẹ OLUWA kọja? ki yio sa gbè nyin., Ẹ máṣe gòke lọ, nitoriti OLUWA kò si lãrin nyin, ki a má ba lù nyin bolẹ niwaju awọn ọtá nyin" (Numeri 13:41, 42). Ṣugbọn wọn ko naani ọ̀rọ Mose, "nwọn fi igberaga gòke lọ sori òke na: ṣugbọn apoti ẹri OLUWA, ati Mose, kò jade kuro ni ibudò" (Numeri 14:44). Ki ni abayọri ijade lọ wọn? "Awọn ara Amaleki sọkalẹ wá, ati awọn ara Kenaani ti ngbé ori-òke na, nwọn si kọlù wọn, nwọn si ṣẹ́ wọn titi dé Horma" (Numeri 14:45). Lẹyin ogoji ọdun, awọn iran ọlọtẹ yii parun ni aginjù gẹgẹ bi ọrọ OLUWA.

## AWỌN IBEERE

1. Iru ọkàn wo ni awọn Ọmọ Israẹli ni ti o mu ki wọn pinnu lati rán amí lọ rin ilẹ naa wo?
2. Ọjọ meloo ni awọn amí fi rin Ilẹ Kenaani wò?
3. Ki ni koko ihin wọn, ki ni wọn si mu pada bọ̀ pẹlu wọn?
4. Iru iṣẹ wo ni iroyin wọn ṣe laaarin awọn Ọmọ Israẹli? Ki ni abayọrisi rẹ?
5. Ki ni Mose ati Aarọni ṣe nitori awọn eniyan naa nigba ti wọn gbọ́ ẹkún wọn?
6. Ki ni Joṣua ati Kalebu ṣe lati mu wọn lọkan le lati gba ilẹ naa? Ki ni iha ti awọn eniyan wọnyii kọ si wọn?
7. Ki ni OLUWA pinnu lati rán si awọn eniyan naa nitori wọn ṣọtẹ si I?
8. Iru ipo wo ni Mose di mu lati da ọwọ idajọ Ọlọrun duro lori Israẹli?
9. Ki ni idajọ ikẹyin ti a ṣe fun awọn ọkunrin ati obinrin ti o ṣọtẹ si Ọlọrun?
10. Ninu awọn ti o to ọmọ ogun ọdun tabi ju bẹẹ lọ ni Egipti, ta ni ninu wọn ti o de Ilẹ Ileri? ki ni ṣe?